Lọ ba a ki o si sọ fun un pe: Dajudaju irẹ ko si ninu awọn ọmọ ina, ṣugbọn o wa ninu awọn ọmọ alujanna

Lati ọdọ Anas ọmọ Mālik – ki Ọlọhun yọnu si i: Dajudaju Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ṣe afẹku Thābit ọmọ Qaysi, ni arakunrin kan wa sọ pe: Irẹ Ojiṣẹ Ọlọhun, maa mu iro rẹ wa fun ọ, ni o ba wa ba a ti o si ba a ni ẹni ti o jokoo si inu ile rẹ, ti o da ori rẹ kodo, ni o wa sọ pe: Ki lo ṣe ẹ? O sọ pe: Aburu ni, o maa n gbe ohun rẹ soke tayọ ohun Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, nitori naa iṣẹ rẹ ti bajẹ, ati pe oun ti wa ninu awọn ọmọ ina, ni arakunrin naa ba pada wa ti o si fun un niroo wí pé o sọ bai bai, o tun wa pada wa ni igba ikẹhin pẹlu iro idunnu ti o tobi, nigba naa ni o wa sọ pe: «Lọ ba a ki o si sọ fun un pe: Dajudaju irẹ ko si ninu awọn ọmọ ina, ṣugbọn o wa ninu awọn ọmọ alujanna».

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ṣe afẹku Thābit ọmọ Qaysi – ki Ọlọhun yọnu si i – o wa beere nipa rẹ, ni arakunrin kan wa sọ pe: Maa mu iro rẹ wa fun ọ, ati idi ti o fi sa, ni o wa lọ si ọdọ rẹ ti o si ba a ni ẹni ti n banujẹ ti o si da ori kodo ninu ile rẹ, ni o wa bi i leere pe: Ki lo ṣe ọ? Ni Thābit wa sọ fun un nkan ti o ṣe e ninu aburu; latari pe oun maa n gbe ohun oun soke tayọ ohun Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a -, ti Ọlọhun si ti ṣe adun fun ẹni ti o ba ṣe iyẹn pẹlu bibajẹ iṣẹ rẹ, ati pe ninu awọn ọmọ ina ni yio wa. Ni arakunrin naa wa pada si ọdọ Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – o si fun un niroo nipa iyẹn, ni Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – wa pa a laṣẹ ki o ṣẹri pada si ọdọ Thābit ki o si fun un ni iro idunnu wipe dajudaju ko si ninu awọn ọmọ ina, ṣugbọn o wa ninu awọn ọmọ alujanna, ati pe lilọ soke ohun rẹ iṣẹda rẹ ni, ati pe o jẹ agbẹnusọ fun Ojiṣẹ Ọlọhun – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – o si tun jẹ agbẹnusọ fun awọn An-soor.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/65073

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee